# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**OSÙ KÁRÙN, ỌDÚN 2022**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

## OṢÙ KÁRÙN 2022
## DÍDÒJÚKỌ ÀWỌN ẸMÍ ÒKÙNKÙN ÀJÀKÁLẸ̀-ÀRÙN TÓKÁRÍ AYÉ (3)

| | |
|---|---|
| 7:00 am – 7:05 am | Àdúrà ìbẹ̀rẹ̀ |
| 7:05 am – 7:20am | Orin Ìyìn àti Ijọ́sìn |
| 7:20 am – 7:35 am | Ijẹ́rì |
| 7:35 am – 7:45 am | Wákàtí Ìṣìpẹ̀ Àdágbà |
| 7:45 a m – 8:45 am | Iṣẹ́ Ìránṣẹ́ |
| 8:45 am - 9:00 am | Ọrẹ àti Ìparí ìpàdé |

1. Gbé Olúwa ga pẹ̀lú mi,
Ẹ̀yin ènìyàn Rẹ,
Kí gbogbo ẹ̀dá alàyè,
Ma yọ̀ l'órúkọ Rẹ̀,
Fún ìfẹ́ tí Ó n fihàn,
Fún ìsinmi l'ọ́kàn wa,
Fún igbàlà kíkún Rẹ̀,
Tìrẹ lọpẹ́.

Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa yin orúkọ,
Olúwa wa títí láíláí,
Àní, títí láíláí,
Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa yin orúkọ,
Olúwa wa títí láíláí,
Àní, títí láíláí,

1. Ẹ̀yin fún ìwà-mímọ́ Rẹ,
Fún ore-ọ̀fẹ́ Rẹ,
Kọrin ìyìn fún ẹ̀jẹ̀ Rẹ,
Tó fi rà wá padà,
Ìfẹ́ ló fi wá wa rí,

Nínú ìrà ẹ̀sẹ̀ wa,
Ó f'ọ̀nà ìyè hàn wá,
Ẹ f'ọpẹ́ fun.

Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa yin orúkọ,
Olúwa wa títí láíláí,
Àní, títí láíláí,
Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa yin orúkọ,
Olúwa wa títí láíláí,
Àní, títí láíláí,

2. Èmí 'ba l'ẹ́gbẹ̀rún ahọ́n,
Nkò lè ròyìn ná tàn;
Ìfẹ́ Rẹ̀ sí mi pọ̀ jọjọ,
Ago 'bùkún mi nkún,
Ore-ọ̀fẹ́ tí kì yẹ́,
Àláfíà bí odò,
Lát'ọ́dọ̀ Olùbùkún;
Ẹ fọpẹ́ fun.

Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa yin orúkọ,
Olúwa wa títí láíláí,
Àní, títí láíláí,
Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa yin orúkọ,
Olúwa wa títí láíláí,
Àní, títí láíláí,

## ỌRỌ̀ AGBÁRA

1. Gbogbo alákoso ilé ìfowópamọ́sí agbára omi tí wọ́n yàn ti ètò ìṣúná mi, Olúwa bá ọ wí lónìí, ku, ní orúkọ Jésù.
2. Gbogbo ibi gíga sátánì, tó n ró àwọn ọ̀tá mi lágbára, ìwọ yóò gba ìparun lónìí, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo ìbápàdé àìmọ̀ pẹ̀lú ẹ̀mí ìpadàsẹ́yìn, dópin nípa agbára tówà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
4. Ẹ̀mí ògbé nípa tẹ̀mí, àkokò rẹ tí dópin nínú ayé mi, jáde nípa iná báyìí, kú, ní orúkọ Jésù.
5. Àwọn to nba ìyanu jẹ́ nínú ayé bàbá mi, látòní lọ, ẹ kò tún ní ṣerere mọ́ nínú ayé mi, nítorínà, ẹ kú, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo iná àjèjì ilé bàbá mi, tí wọ́n yàn lòdì sí ògo ayé mi, kú nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo ahọ́n tóní ifòróróyàn sátánì, tó n sọ̀rọ̀ ìkùnà sínú ayànmọ́ mi yóò gbẹ nípa iná lónìí, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ

**Ìjẹ́wọ́: Orin Dáfídì 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Agbára ìyówù tó n lọ̀, tó sì tún n po àwọn nkan pọ̀ lòdì sí mi, ṣòfò pẹ̀lú àwọn ohun èlò rẹ, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo ọ̀tá ayọ̀ mi tíkò fẹ́ ronúpìwàdà, kú sínú itìjú, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo ìka ọ̀tá tí wọ́n yàn láti dá ayànmọ́ mi dúró, gbiná báyìí, ní orúkọ Jésù.
6. Àwọn agbára ibi ilé bàbá mi, tí wọ́n yàn láti fọ atẹ̀gùn sí dídi ẹni nlá, ṣubú lulẹ̀, kú, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo ọ̀tá àwọn àlá wólì mi, ya wèrè, ko sì kú, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ ỌRỌ̀ NÁÀ

**2 Kọ́ríntì 9:8:** Ọlọ́run sì lè mú kí gbogbo ore-ọ̀fẹ́ ma bísi i fún nyin; kí ẹ̀yin, tí ó ní ànító ohun gbogbo nígbàgbogbo, lè ma pọ̀ si i ní iṣẹ́ rere gbogbo:

**Jerémíàh 29:11:** Nítorí èmi mọ̀ ìrò tí mo rò si yín, li Olúwa wí, àní ìrò àláfíà, kì sí íṣe fún ibi, láti fún yin ní ìgbà ìkẹyìn àti irètí.

**Fílíppì 4:19:** Ṣùgbọ́n Ọlọ́run mi yóò pèsè ní kíkún fún gbogbo aìní yín, gẹ́gẹ́ bí ọrọ̀ Rẹ nínú ògo nínú Krístì Jésù.

**Rómù 15:13:** Njẹ́ kí Ọlọ́run irètí kí Ó fi gbogbo ayọ̀ òn àláfíà kun yín ní gbígbàgbọ́, kí ẹ̀yin kí ó lè pọ̀ ní irètí nípa agbára Ẹ̀mí Mímọ́.

**Orin Dáfídì 103:1-4:** Fi ibùkún fún Olúwa, ìwọ ọkàn mi, àti gbogbo ohun tí ó wà nínú mi, fi ibùkún fún orúkọ Rẹ̀ mímọ́. Fi ibùkún fún Olúwa ìwọ ọkàn mi, má sì ṣe gbàgbé gbogbo ore Rẹ̀: Ẹnití Ó dárí gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ rẹ jì; Ẹnití Ó sì tán gbogbo àrùn rẹ; Ẹnití Ó ra ẹ̀mí rẹ kúrò nínú ìparun; Ẹnití Ó fi ìṣeun-ìfẹ́ àti ìyọ́nú dé ọ lí adé;

**Orin Dáfídì 16:11:** Ìwọ Ó fi ipa ọ̀nà ìyè hàn mí; ní iwájú Rẹ̀ li ẹ̀kún ayọ̀ wà: lí ọwọ́ ọ̀tún Rẹ̀ ní dídùn-inú wà láíláí.

**Orin Dáfídì 118:24:** Èyí li ọjọ́ tí Olúwa dá: àwa ó ma yọ̀, inú wa yóò sì ma dùn nínú rẹ.

**1 Jòhánnù 2:14:** Èmí kọ̀wé si yín, ẹ̀yin bàbá, nítorítí ẹ̀yin ti mọ ẹnití Ó wà lí àtètèkọ́ṣe. Èmí ti kọ̀wé si yín, ẹ̀yin ọ̀dọ́mọkùnrin, nítorítí ẹ̀yin lí agbára, tí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run sì dúró nínú yín, tí ẹ sì ṣẹ́gun ẹni búburú nì.

**Orin Dáfídì 126:5:** Àwọn tí nfi omíjé fun irúgbìn yóò fi ayọ̀ ka.

**Orin Dáfídì 119:111:** Ẹ̀rí Rẹ ni ogún mi láíláí: nítorí àwọn li ayọ̀ inú mi.

**Òwe 17:22:** Inú dídùn mú ìmúláradá rere wá: ṣùgbọ́n ibìnújẹ́ ọkàn mú egungun gbẹ.

**3 Jòhánnù 1:4:** Èmi kò ní ayọ̀ tí ó pọ̀ju èyí lọ, kí èmi kí o ma gbọ́ pé, àwọn ọmọ mi nrìn nínú òtítọ́.

**2 Kọ́ríntì 6:10:** Bí ẹnití ó kún fún ibìnújẹ́, ṣùgbọ́n àwa nyọ̀ nígbàgbogbo; bí tálákà, ṣùgbọ́n àwa nsọ ọpọ̀lọpọ̀ di ọlọ́rọ̀; bí ẹnití kò ní nkan, ṣùgbọ́n àwa ní ohun gbogbo.

**Oníwàsú 9:7:** Ma bá tìrẹ lọ, ma fi ayọ̀ jẹ oúnjẹ rẹ, kí o sì ma fi inú dídùn mu ọtí-wáínì rẹ; nítorípé Ọlọ́run tẹ́wọ́gba iṣẹ́ rẹ nísisìyí.

<u>ÀDÚRÀ SÓRÍ ÀWỌN AWÒRÁN</u>

1. Awòrán mi, mo lò ọ́ gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà ìbápàdé, ibi ìyówù tí wọ́n bá ṣètò sínú rẹ kòní farahàn, ní orúkọ Jésù.
2. Ìwọ awòrán mi, gbọ́ ọ̀rọ̀ Olúwa; o kòní gbọ́ ti ibọ̀dè mọ́, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo ìfayà àti afọ̀ṣẹ, tí wọ́n ṣe sí ayé mi nípa awòrán mi, padà sọ́dọ̀ ẹnití ó rán ọ, ní orúkọ Jésù.
4. Mo lo awòrán mi yìí gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà ìbápàdé, Bàbá mi, jẹ́ kí ìtàn mi yípadà sí rere, ní orúkọ Jésù.
5. Pẹpẹ-kí-pẹpẹ sátánì tí àwọn awòrán mí wà lóri rẹ̀, gbiná báyìí, ní orúkọ Jésù.
6. Ojúbọ ibi ìyówù tí àwọn awòrán mí wà nínú rẹ, gbiná báyìí, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo àlúfà ibi, tó nlo awòrán mi lòdì sí ayànmọ́ mi, ṣubú lulẹ̀ kú, ní orúkọ Jésù.
8. Gbogbo agbára tó n bẹ àwọn agbára onígun-mẹ́ta wò, pẹ̀lú awòrán mi lọ́wọ́ fún ibi, túká, ní orúkọ Jésù.
9. Gbogbo agbára òkùnkùn tó n lo awòrán mi fún afọ̀ṣẹ, ṣubú lulẹ̀ kú, ní orúkọ Jésù.
10. Ọfà ibi ìyówù tí wọ́n ta sí awòrán mi, ta padà, ní orúkọ Jésù.
11. Mo pàṣẹ kí awòrán mi di ẹṣẹ-iná tíkò ṣe fọwọ́kàn, ní orúkọ Jésù.
12. Agbárákágbara tó nlo awòrán mi lòdì sí mi, gba itìjú, ní orúkọ Jésù.
13. Mo fi ara mi sínú àpò-ìwé iná Ọlọ́run Èlíjàh, mo fi ara mi sínú ibú ẹ̀jẹ̀ Jésù, gbogbo èròngbà òkùnkùn lòdì sí ìwàláàyè mi, di asán nípa agbára tówà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
14. Gbogbo ẹ̀mí Gólíátì tó n dúkokò mọ́ ìwàláàyè mi nípa lílo awòrán mi, mo gbé agbára rẹ sin, ní orúkọ Jésù.
15. Àjọ àjẹ́ tàbí ìkórajọpọ̀ òkùnkùn ìyówù, ló n lo awòrán mi láti fi yọ ayé mi lẹ́nu, gbiná, jó di éérú, ní orúkọ Jésù.
16. Olúwa, Ìwọ ni ògo mi àti olùgbé orí mi sókè, pàṣẹ ìgbédìde atòkèwá lé orí mi, ní orúkọ Jésù.
17. Agbárákágbara tó nwo awòrán mi nínú awòjìjí, gba ifọ̀jú, ní orúkọ Jésù.

18. Ohunkóhun tó jẹ́ tèmi tàbí tó n ṣaṣojú mi lórí pẹpẹ àjẹ́ ìyówù, (àwọn ohun ìní mi, àwọn awòrán mi, aṣọ mi, owó mi, orúkọ mi, ẹ̀yà ara mi ìyówù, àwọn eèkáná tàbí irun mi, nínú afẹ́fẹ́, lórí ilẹ̀, lábẹ́ ilẹ̀, nínú àwọn omi tàbí lábẹ́ omi, nínú odò, iyẹ̀pẹ̀, òkun, níbojì, láwọn oríta-mẹ́ta, níwájú àwọn orìṣà, nínú àjọ àwọn àjẹ́ tàbí ní tẹ́mpílì sátánì), gba ìparun nípa iná Ẹ̀mí Mímọ́, ní orúkọ Jésù.
19. Gbogbo ibòjú àti ohun tí a fi n mọ bí ojú ọjọ́ ṣe rí tẹ̀mí, jígí tẹ̀mí, ẹ̀rọ ìgba ọ̀rọ̀ sílẹ̀ tẹ̀mí, ẹ̀rọ iyàwòrán tẹ̀mí, ẹ̀rọ agbọ́rọ́kàyé tẹ̀mí àti gbogbo ohun ìní tẹ̀mí, ti sátánì ti dẹ lòdì sí mi láti tọpinpin mi, fọ́ sí wẹ́wẹ́, ní orúkọ Jésù.
20. Mo jẹ́ ọmọ Ọlọ́run, mo sì tùn jẹ́ ara ẹ̀yá ara Jésù. Ẹnikẹ́ni tó bá fọwọ́kàn mí fọwọ́ba Ẹyinjú Jésù. Kò sí ohun ìjà tí a ṣe lòdì sí ayé mi tí yóò gba ọnàkọnà ṣe nkan, àti pé, gbogbo ahọ́n tó bá dìde lòdì sí mi ní ìdájọ́ ni a ó dálẹ́bi, wọn ó sí gba ìparun pátápátá, ní orúkọ Jésù.
21. Mo lo awòrán yi láti sọtẹ́lẹ̀ sórí ayé mi, yóò dára fún mi. Èmi yóò mú ayànmọ́ mi ṣẹ. Èmi kò ní kú láìṣepé, a ṣe àjọyọ̀ mi,. Agbára òkùnkùn kò ní kó ìdibàjẹ́ bá ayé mi. Èyí ni mo gbàdúrà ní orúkọ nlá Jésù Krístì Olúwa (Àmín).